# Tani Iwọ Fi Eyi Pe?

Phoenix, Arizona, USA

Ọjọ 27, Oṣu Kejila, Ọdun 1964

1 Ẹ kaarọ eyin ọrẹ. Mo ka eyi si anfaani ni tootọ lati wa ni ile ijọsin yii. Mo si fẹran orukọ rẹ lati ibẹrẹ pẹlu. A n pe ni "Orukọ Jesu." Mo fẹran iyẹn. Mo si ro pe.... Orukọ ti a fi ràmí pada ni iyẹn, orukọ ololufẹ tii ṣe Jesu Oluwa. Ati lẹyinnaa lati wa ni ibiyi pẹlu awọn ọrẹ mi dáradára, ti a pejọpọ ni òwúrọ̀ ọjọ Aiku dáradára yii ni Phoenix. Nko mọ ibi kan ti emi ko ba kuku wa, bi ko ba jẹ ninu Ogo pẹlu gbogbo yin. Ati pe iyẹn ni iṣẹlẹ nla ti a n reti niwaju ni ọjọ kan.

Ati pe Mo ni ipe fun alaisan kan, lati goke wa sibi, loni. Mo sì ń bá Arákùnrin Outlaw, ọ̀rẹ́ mi ọ̀wọ́n sọ̀rọ̀, ó sì pè mí tifẹ́tifẹ́ láti wá. Ati gbogbo awọn ojiṣẹ́ nibi ni Phoenix ti dara pupọ si mi.

2 O maa n jẹ iyanu fun mi nigba miran idi ti mo ṣe kó wa si Tucson. Mo ti wa ni nibẹ fun ọdun mẹta, ati pe a ko pe mi si ori pẹpẹ kankan ri lati waasu. Nitorinaa Mo ro pe Mo ti ... Lati kan ṣe abẹwo mi nibi ni Tucson… tabi nibi ni Phoenix, nibiti a ti kími-kaabọ. O dara, boya wọn yoo le bami ṣe nigba diẹ…. Ṣe o mọ, mo waasu nisalẹ nibẹyẹn ni alẹ kan, ati pe mo waasu fun wakati mẹta; Abajọ ti wọn ko pe mi pada.

Ṣùgbọ́n mo ní irú ìmọ̀lára bẹ́ẹ̀ nínú ọkàn mi fún Ọlọ́run àti àwọn ènìyàn Rẹ̀. Mo si lọra, atipe mo wa nbẹru pe emi yoo fi nkankan silẹ lai mẹnu ba, ti n kii yoo lee sọ, mo si pa iwaasu bi mẹta tabi mẹrin pọ sinu ọkan. Nitorinaa dajudaju … si ẹyin eniyan ti o wa nibẹ, Mo tọrọ gafara fun mimu yin duro pẹ pupọ. Ko yẹ fun mi lati ṣe bẹẹ.

3 Ati pe inu mi dun ni owurọ yi lati wa nibi pẹlu Arakunrin Carl Williams, ati Jimmy kekere nihin, ati awọn akọrin, ati ọrẹ mi awọn arakunrin Moseley; wo Arakunrin John Sharrit, ati ọpọlọpọ awọn ọrẹ mi; Arákùnrin Pat Tyler, níhìn, láti ọ̀nà jíjìn ní Kentucky, àti ọ̀pọ̀ àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀ láti pé jọ sí àpéjọ yìí ní òwúrọ̀ yìí. Wo, mo ri ọpọlọpọ awọn ọrẹ mi lati Tucson ati bẹẹbẹẹ lọ, lo joko nibiyi.

Mo n ronu nipa ọjọ kan nigbati gbogbo eyi ba pari, lẹyin naa a o pejọ nibiti a kii yoo ṣe alaigbọ awọn orin didun wọnyi, woo. Mo ṣẹ̀ṣẹ̀ ṣàkíyèsí pé ọmọ Arákùnrin William, ti o joko nibẹ yẹn, ó jẹ̀rí lálẹ́ ọjọ́ kan ní Ramada Inn. Ati pe Mo ro pe o fẹrẹ sunmọ ẹsẹ bata mẹfa ni giga. Ṣùgbọ́n mo sọ fún yín, lẹ́yìn ẹ̀rí yẹn, mo gbàgbọ́ pé ó ga ní ẹsẹ̀ bata mẹwa. O kan…. Mo mọ rírì ohun ti ọmọkunrin naa sọ, iru ẹri iyanu bẹẹ.

4 Nígbà tí mo gbọ́ àwọn ọ̀dọ́ dáradára wọnyi tí wọ́n ń jẹ́rìí nípa ìgbàgbọ́ wọn tí ó dá lórí Krístì…. Mo sì ń darúgbó, èmi sì… ní ọjọ́ kan mo ní láti siwọ́ kí n sì lọ sí ilé. Ti mo si ri awọn ọdọmọkunrin wọnyi ti o nbọ ti o ti ṣetan, ti wọn si ti mura lati gbe ni ibi ti mo lọ kuro .... Ati pe iyẹn ni ọna ti a nfi ṣee. Iyẹn ni ọna ti igbesi aye ti gbe kalẹ. Pe awa ... iran kan yoo goke... baba ati iya. Wọ́n sì ń tọ́ àwọn ọmọ wọn dàgbà, wọ́n sì rí wọn tí wọ́n ń gbéyàwó; àwọn ọmọ-ọmọ sì ńde. Ati lẹhin igba diẹ, baba ati iya lọ si eruku. Ati lẹyin naa, nipasẹ akoko yẹn, awọn ọmọ naa tun ti ṣetan lẹẹkansi fun awọn ọmọ-ọmọ ti wọn; ati lẹyin naa, wọn si sọ kalẹ lọ. Ṣugbọn ajinde nla gbogbogbogboo kan yoo wa ni ọkan ninu awọn ọjọ wọnyi. A o pe gbogbo wa si iwaju Ọlọrun lati royin ohun ti a ṣe pẹlu ohun ti Ọlọrun fi fun wa: Jesu Kristi. Nitorinaa, inu mi dun pupọ lati mọ pe mo n gbe ni iran yii pẹlu iru ọpọ eniyan ti o dara, iyẹn ni ayika agbaye, ti mo ti pade. Mo kan dupẹ lọwọ Ọlọrun. Ati ni ọjọ kan nigbati ipe mi ba de, emi yoo ni lati lọ pade awọn iṣẹ ti mo ti ṣe. Mo fẹ ki gbogbo wọn lè jẹ́ fún ògo ati ọlá Ọlọrun.

5 Ọpọlọpọ nkan lo wa bi a ti n sunmọ ọdun titun ti mo lati fẹ gbagbe, ṣugbọn mo mọ pe mo ti jẹwọ wọn bii asiṣe fun Un, O si fi wọn sinu okun igbagbe, Oun kì yóò rántí wọn mọ láéláé. Bayi wo, a ko ṣe wa ni ọna yẹn, a o ranti nigbagbogbo. A le dariji ara wa, ṣugbọn a ko le gbagbe nipa rẹ nitori a ṣe wa yatọ. Ṣugbọn Ọlọrun le dariji ki o si gbagbe rẹ. Ó lè pa á rẹ́ bíi pé kò rí bẹ́ẹ̀ rí. Wo? Nitori O ni aaye si okun igbagbe, ṣugbọn awa ko ni aaye si. Ronú nípa rẹ pé Ọlọ́run kò tilẹ̀ lee rántí pé a ti ṣẹ̀ rí. Ronú nípa ìyẹn! Ẹgbẹ akọrin, ẹyin ọmọde, ti... iyẹn nkọ? Ọlọrun paapaa ko ranti pe a ti ṣẹ ri. Kiyesi i, O le gbagbe gbogbo nkan naa, ati pe ko ni mu wa si iranti mọ. Ṣe iyẹn kii yoo jẹ nkan kan bi?

6 Eleyi kii ṣe ibi to wa fun awada. Nko gbagbọ ninu ẹfẹ tabi awada ni.... O ran mi leti ọrẹ mi kan. O ti lọ sinu ogo bayi. Ṣugbọn o sọ itan kekere kan ni akoko kan, nipa tọkọtaya kan ti wọn ko lọ si ilu nla ati ... lati abule. Nwọn si ní a .... Awọn ọdọ tọkọtaya yii ní baba agba kan, eniti o si n gbina fun Ọlọrun ni. Nitorina ọmọbirin naa (baba rẹ niyẹn) nitorina o ti darapọ pẹlu awọn alafẹ eniyan. O mọ, nibi ti wọn ti ni gbogbo iru awọn ere idaraya ti o gbafẹ. Ati nitorinaa, oun yoo ni iru ere afẹfẹyẹ̀yẹ̀ kan ni ọjọ yẹn ni ile rẹ.

Ati baba rẹ, lẹyin ti o ba ti jẹ ounjẹ ọsan rẹ tan, yoo gbe Bibeli ti o si wo inu yara lati ka a diẹ. Ó sì gbe kalẹ̀, yóò sì sunkún, yóò sì pariwo, yóò sì kigbe, yóò sì tẹ̀ síwájú bayẹn, yóò sì dìde, ó sì gbé awò oju rẹ̀ wọ̀, yóò sì tún kà. Lẹyin naa yoo wa nkan, yoo fi awo oju rẹ silẹ, yoo si bẹrẹ si sọkun ati lati maa kigbe. Omobinrin rẹ sọ pe, "Iyẹn yoo da ayẹyẹ mi duro nitori naa, ... Mo ni lati ṣe nkan kan pẹlu baba, ati pe emi ko mọ kinni n o ṣe." Torí náà, ó pinnu pé oun yoo jẹ́ ki ó lọ sí òkè, kó sì wa nibẹ.

7 Ó sì bẹ̀rẹ̀ sí ní ronú pé, "Ó dáa nisisinyi, mi ò lè fún un ní Bíbélì rẹ̀, torí pé ó máa ṣe ohun kan náà níbẹ̀." Nitorina o kan fun u ni iwe Geography atijọ kan, o si rán a lọ sibẹ. O sọ pe, "Baba, wo awọn aworan ayika agbaye ati awọn nkan bẹẹ nigba ti a n ṣe ayẹyẹ." Ó sì sọ pé, "A ò ní pẹ́ jù. A o wa si isalẹ…. Iwọ o sọkalẹ wa lẹyin igba diẹ." O sọ pe, "Mo mọ pe iwọ ko fẹ lati wa ni ayika nibiti gbogbo awọn obinrin wa."

O ni, "Rara, o dara, Oyin. Emi yoo lọ soke nibẹ."

Nitorina o ... O ṣeto ina ati aaye diẹ fun u. O si ro pe, "O dara, iyẹn yanju rẹ. Bayi, yoo kan wo awọn aworan naa, yoo ka diẹ ninu iwe geography (ẹkọ-aye), lẹyin igba diẹ yoo sọkalẹ. Ati pe yoo si dara bẹẹ."

8 Nitorina ni akoko ti wọn wa ni arin ohun ti wọn nmu lemonade alawọ pinnkin, o mọ, ati pe wọn nṣe ayẹyẹ wọn.... O dara lẹhin igba diẹ, ile bẹrẹ si mì, ati pe ọkunrin arugbo naa bẹrẹ si sare soke ati isalẹ o n kigbe, o si nfo. Ó sì rò ó pé, "Kí ló ṣẹlẹ̀ sí i? Kò ní Bíbélì níbẹ̀yẹn... O gbọdọ ti ri Bibeli dimu."

Nítorí náà, ó sáré gòkè lọ, ó sì sọ pé, "Baba!" Ó sọ pé, "Kì í ṣe Bíbélì lò ń kà yẹn. Ìwe Geography niyẹn."

O sọ pe, "Mo mọ, Oyin. Mo mọ! Ṣùgbọ́n," ó sọ pé, "Ṣe o mọ̀, ní ọjọ́ kan tí mo ń kà nínú Bíbélì níbi tí Jésù ti sọ pé Óun fi àwọn ẹ̀ṣẹ̀ wa sínú òkun ìgbàgbé, wò ó, kò sì ní rántí wọn mọ́. Mo sì ń ka ìwé ni ibi tí wọ́n ti sọ pé wọn kò lè rí ìsàlẹ̀ òkun láwọn ibì kan, nínú Ìwé Geography yi." O sọ pe, "Sa ro o, wọ́n ṣì ń lọ."

Ìyẹn sì mú inú rẹ̀ dùn. Nitorina o le ri Ọlọrun nibikibi ti o ba wo. Wo, ti o ba kan wo yika, ohun gbogbo yoo sọrọ fun Un.

9 Ní báyìí, ní ti tòótọ́, mo sọ fún Arákùnrin Outlaw pé, "Kí ni kí n sọ nípa rẹ̀ ní òwúrọ̀ yìí? Njẹ o ti waasu tirẹ nipa Keresimesi? "O sọ pe, "Bẹẹni."

Mo sọ pé, "Ìwaasu rẹ fun Ọdún Tuntun nkọ?"

"Bẹẹkọ."

Nitorinaa, Mo ni awọn ilana diẹ nibiyi boya ti mo ba gba ifiwepe si ibikan, emi yoo waasu mi nipa ti Ọdun Tuntun. Mo ro pe Emi yoo fi iyẹn silẹ fun Arakunrin Outlaw fun tirẹ, ni ọsẹ ti n bọ.

Nitorinaa mo ro pe boya emi yoo pada sẹhin lori ọrọ kekere kan eyi ti o le gba wa fun iṣẹju diẹ, bi Oluwa ba fẹ. A si gbẹkẹle pe Oun yoo bukun wa. Mo fẹ́ dúpẹ́ lọ́wọ́ Arákùnrin Outlaw àti ìjọ tó wà níhìn-ín, fún pípe mí láti sọ̀rọ̀ níbí. Ati Emi.... Gẹgẹ bi Arakunrin Outlaw ti sọ, pe "ọrẹ wa ko tii parẹ," ṣugbọn oore-ọfẹ Ọlọrun ti pa wa mọ ni gbogbo awọn ọdun wọnyi. Eyi ni ile ijọsin akọkọ ti o pe mi, eyi ti mo tii wa si, ni Phoenix.

10 Mo mọ ... Mo gbagbọ pe mo n wo Arakunrin Trow, nibi. Emi ko ni idaniloju ... ẹni ti o joko ni ila iwaju. Ṣe otitọ ni, Arakunrin Trow? Mo gbagbọ pe o jẹ ni akoko yẹn. Mo ni awọn ohun kekere kan ti o fun mi nigba yẹn; kekere ... nwọn mọ o jade tabi nkankan. Ṣe o mọ, awọn idẹ kekere kan lati oke nibi ti o ngbe. Ati pe o wo yika ... Mo si nkọminu pe kini yoo jẹ ni owurọ yẹn nigba ti a ba rekọja, o mọ, ati lati rii eniyan… wọn sọ pe, "O dara, nibẹ…."Ṣe O mọ, a o yatọ pupọ nigba naa, ju ohun ti a nṣe ni bayi. A yoo…. Otitọ ni. A kii yoo ni àmì ẹṣẹ tabi ọjọ ogbó. A yoo jẹ pipe. Oh, Mo nireti fun akoko yẹn (Iwọ kọ?) nibiti gbogbo wahala yoo ti dopin.

11 Ati nisisiyi, mo ni iṣẹ-iranṣẹ kan lati ọdọ Ọlọrun eyi ti mo lero. Ati pe mo ... Emi ko fẹ lati yatọ, ṣugbọn mo gbọdọ jẹ olootọ. Ati pe ti emi ko ba sọ ohun ti o damiloju, o ko le ni igbẹkẹle ninu mi. Nitoripe Emi yoo jẹ bii ọdalẹ tabi agabagebe. Ati pe mo fẹ lati jẹ ohun miiran to yatọ si iyẹn, woo. Mo lè pàdánù àwọn ọ̀rẹ́ díẹ̀ lórí ilẹ̀ ayé, ṣùgbọ́n mo fẹ́ dúró ṣinṣin sí ohun tí mo gbà gbọ́, sí ohun tí mo rò pé ó tọ́.

12 Bayi, ni awọn ọdun sẹyin, o rọrun pupọ nigbati mo kọkọ bẹrẹ; ati awọn ami, ati ifiranṣẹ, ati iwaasu. Nibikibi ni o ṣi silẹ, "Wá! Wa! Wa! Wá!" Ṣugbọn lẹyin naa, ṣe o rii, gbogbo ami otitọ lati ọdọ Ọlọrun ni isẹ-iranṣẹ kan, ohùn kan. Woo, o tẹle e. Ti ko ba jẹ ... Ọlọrun koni fi ohunkohun bi iru iyẹn fun igbadun lasan. O fi ohun kan ranṣẹ lati fanimọra si ohun ti O n fẹ lati sọ. Bi a ti ni orin iyanu yii ti awọn akọrin kọ; kini yẹn jẹ? Lati mu ki ara awọn eniyan balẹ fun isẹ-iranṣẹ ti n bọ.

Iyẹn jẹ ohun ti àmì nṣe. Mósè ní àwọn àmì tí a sọ nípa rẹ ni alẹ kan, àwọn àmì náà sì ní ohùn. Ati awọn ... nigbati ohùn sọrọ ... Jesu naa si jade pẹlu O nmu awọn alaisan larada. Ọkunrin nla ni. Ṣugbọn nígbà tí ó tó àkókò tí wolii náà tí ó wà lórí ilẹ̀ ayé …

Ti kò tíì ní ọ̀kan fún irinwo ọdún, Oun si niyi lori ilẹ-aye tó sì ń ṣe iṣẹ́ àmì. Nigba ti O jẹ "ẹni rere," gbogbo eniyan fẹ Ẹ. Ṣùgbọ́n nígbà tí iṣẹ́ tí ó tẹ̀lé àmì yẹn, ohùn náà... nígbà tí Ó joko lọ́jọ́ kan, tí ó sì wí pé, "Èmi àti Baba mi jẹ́ ọ̀kan." Oh, kasa! Ohun ti o yatọ niyẹn. Wọn ko fẹ iyẹn, wo.

Ati pe ... bii aye ṣe ri niyẹn, ẹyin ọrẹ, wo... ohunkohun ti wọn le ri, ti wọn ba le ran ara wọn lọwọ pẹlu rẹ, o rii .... Ti wọn lero pe niwọn igba ti ko ba da yọ wọn lẹnu, kilode, wọn yoo ṣe. Ṣugbọn nigbati o ba de akoko ti

wọn ni lati yi awọn ero wọn pada nipa awọn nkan, iyẹn ni igbati wahala a de.

13 Nisinsinyi, wo, a n kọ ile kan, kii ṣe odi kan. Awọn akọle fẹ lati mu ila awọn bulọọki ki o kan lọ taara. Eyikeyi Ọmọle le kọ iyẹn. Ṣugbọn a nilo Ọmọle onimọ-ẹrọ gidi kan lati yi igun ile, Nigbati o ba ni lati ge igun ile naa, akoko ti o gba niyẹn ... o fihan boya o jẹ ọmọle okuta tabi bẹẹ kọ́; nigba ti o ba le ge awọn igun ile pẹlu ti o si tẹsiwaju ninu awọn iyokù ile, ṣugbọn ge igun naa. Bayi lori awọn igun wọnyi ni igba ti wahala maa wa. Awọn ọmọle fẹ lati tẹsiwaju lati kọle bẹẹ. ṣugbọn a ko kọ odi kan; ṣugbọn, ile.

Bayi bi a ti sunmọ eyi, ni owurọ yi, gbadura fun mi, ati pe emi yoo ... Mo gbadura fun yin nigbagbogbo. Wàyí o, ẹ jẹ́ kí a tẹríba fún ìṣẹ́jú kan péré níwájú Jèhófà Ọlọ́run ńlá. Ati pe a mọ àitótán wa; gbogbo wa pata. Ati pe ko si ọkan ninu wa nibi ti ko nilo. Ati pe mo kọminu, nigba ti a ngbadura, ti ẹnikẹni ba wa ninu nyin ti o nilo ohun pataki kan?

14 O mọ, Iwọ Ọlọrun ailopin, gẹgẹ bi mo ti sọ nibi ni Phoenix ni ọjọ kan ninu ipade ni isalẹ nibi…. Gẹgẹ bi tẹlifisan, O n bọ, Kristi wa nibi ninu ile bayi. Wo, gbogbo irin ti o nṣe, ni gbogbo igba ti o ba ṣẹ oju rẹ, kii yoo ku. O wa ninu awọn igbi ti afẹfẹ. Tẹlifisan ko ṣe iyẹn. O kan gbe igbi yẹn soke, o si gbe jade lori iboju kan. O wa nibẹ. O wa nibẹ nigbagbogbo. Gbogbo ohun ti o ṣe wa laaye nigbagbogbo, ninu afẹfẹ. Ni bayi, ṣe o rii ohun ti a jẹ wa nibi idajọ?

Nitorina, Ọlọrun wa nibi ni ọna kanna. A ko ri O, gẹgẹ bi a ko ti ri awọn aworan tẹlifisan wọnyẹn. Yoo gba apo (tube) kan tabi kristali kan lati mu ohun naa jade, ki o tun aworan naa ṣe ati bẹẹbẹẹ lọ. Ìyẹn wà níhìn-ín nígbà tí Ádámù wà lórí ilẹ̀ ayé, ṣùgbọ́n a ṣẹ̀ṣẹ̀ rí ni. Ọlọrun wa nibi laarọ yi. Ati pe ni ọkan ninu awọn ọjọ wọnyi, nigba ẹgbẹrun ọdun, a o mọ. Yoo daniloju gidi ju tẹlifisan tabi awọn nkankan lọ, pe O wa nibi ipade ni owurọ yii.

Nisinsinyi nigba ti a... lori ero yẹn, mọ ohun ti o nilo ninu ọkan rẹ, ki o kan gbe ọwọ rẹ soke si I. Ṣe iwọ yoo ṣe iyẹn? Sọ pe, “Oluwa,...” Ati ninu ọkan rẹ, ronu ero naa.

15 Nisisinyi, Baba ọrun, ọna kanṣoṣo yii ni a ni, ati pe iyẹn jẹ nipasẹ ọna adura. Awa si nbọ loruko Jesu Oluwa. A ko yẹ lati mi eemi orukọ naa, lati lo o. A kii ... ko tumọ si pe a ro pe a yẹ, ṣugbọn nitori pe a ti pe wa lati ṣe e. Nigbati a si mọ̀ eyi pe, O wipe, “Bi ẹyin ba bi Baba leèrè ohunkohun ni orukọ mi, Emi o ṣe e. Ati pe a jẹ ... ti igbagbọ wa ba le duro lẹyin iyẹn nikan, pe o jẹ Ọrọ Rẹ ati ẹniti Oun jẹ, nigba naa a ni idaniloju lati gba ohun ti a beere fun. O ti ri gbogbo ìbéèrè. O ti ri ọwọ mi. O mọ ibeere mi.

Baba, mo gbadura fun olukuluku wọn. Pe ohun gbogbo ti wọn nilo ... Oluwa, Emi ko gbagbọ pe ẹgbẹ kan bi eleyi yoo beere fun ohunkohun ti ko tọ́. Yoo jẹ fun nkankan fun ilosiwaju ijọba wọn, o le jẹ fun iwosan ara wọn; ati ni ṣiṣe eyi, wọn fẹ ... tabi oye tiwọn. Wọ́n fẹ́ bẹ́ẹ̀ kí wọ́n lè tẹ̀ ìjọba Ọlọ́run síwájú.

16 Mo si gbadura, Ọlọrun, pe ki a le mu awọn ibeere olukuluku ṣẹ. Bukun ile ijọsin yii, Oluṣọ-aguntan rẹ, awọn ẹlẹgbẹ rẹ, ati awọn diakoni, awọn alabojuto, gbogbo awọn ọmọ ijọ rẹ, awọn atipo, alejo. Wọn kii ṣe alejo, Oluwa. Gbogbo wa ni ọmọ rẹ nipasẹ ore-ọfẹ ati nipasẹ Kristi. A si gbadura pe ki O fun wa ni owurọ yii ounjẹ iye nisisinyi, ki a le kuro nihin pẹlu oye pe awọn ibeere wọnyi ti a beere ni a ti fun wa.

Fi ibukun fun Ọrọ na, Oluwa, bi mo ti nka. Ko si eniyan ti o pe tabi ti o to tan lati tumọ Ọrọ naa. Jòhánù rí ìwé náà lọ́wọ́ ẹni tí ó jókòó lórí ìtẹ́ náà, kò sì sí ẹnìkan ní ọ̀run, tàbí lórí ilẹ̀ ayé, tàbí nísàlẹ̀ ayé tí ó yẹ láti wo ìwé náà pàápàá. Ṣugbọn ọkan ninu awọn àgba na wipe, “Kiyesi i, kiniun ẹ̀ya Juda ti bori.” Nígbà tí Jòhánù wo lati ri kìnnìún, ó rí Ọ̀dọ́ Àgùntàn kan tí wọ́n ti pa, Ọ̀dọ́ Àgùntàn ti o nsun fun ẹ̀jẹ̀ kan jáde wá, ó sì mú ìwé náà, ó gun orí ìtẹ́, ó sì jókòó. Gbogbo àwọn olókìkí Ọ̀run sì mu adé wọn kúrò lórí wọn, wọ́n tẹrí ba, wọ́n sì mọ̀ pé Ó yẹ.

Oluwa, a gbadura pe ki O wa si ori itẹ ọkan wa laarọ yi. Gun ori itẹ soke ki o si gba gbogbo ero ti a ni, ki o si mu Ọrọ naa ki o si ba wa sọrọ ki a le mọ sii nipa Rẹ ati eto Rẹ ninu aye wa. A beere ni orukọ Jesu. Amin.

17 Nisisinyi, ti o ba fẹ lati ṣi Bibeli si .... Iwe-mimọ ti a ri ninu Matteu ori ikọkanlelogun, a o si bẹrẹ pẹlu… Mo ro pe a o ka ẹsẹ kẹwa ati ikọkanla ti ori ikọkanlelogun. Ṣe eyi to dara, nigbati o ba lọ si ile, ti o ko ba ti ṣe bẹẹ tẹlẹ ni akoko awọn isinmi yii, ti o ba ka ori yii jalẹ. O dara pupọ. O dara gidigidi. Paapaa, fun akoko yii, ati pẹlu iṣẹ-iranṣẹ ti mo nireti pe Ẹmi Mimọ jẹ ki n mu fun yin wa ni owurọ yii.

Ṣakiyesi ẹsẹ kẹwaa bi a ti n ka, ati ikọkanla:

Nigbati o si de Jerusalẹmu, gbogbo ilu mì, wipe, Tani eyi?

Ọpọ ijọ eniyan si wipe, Eyi li Jesu wolii ti Nasareti ti Galili.

Bayi iyẹn ni ... Ki Ọlọrun fi ibukun si kika Iwe Mimọ ti Ọrọ Rẹ.

18 Nisisinyi a ti mọ akoko ti o jẹ, ati pe ọpọlọpọ ninu nyin ti mọ ori kan pato ti iwe mimọ yii. O jẹ lori ... nitootọ ni ọjọ ti Kristi wa si Jerusalẹmu, o gun kẹtẹkẹtẹ kekere yii. Ati awa.... Àlàyé kan wa ti o sọ pe "kẹtẹkẹtẹ funfun kan ni." Emi yoo foju inu wo, gẹgẹbi apẹrẹ bibọ Rẹ lẹẹkeji lori ẹsin kan. Ní àkókò yẹn, wòlíì náà sọ pé, "Yóò gùn...Ọba rẹ ń bọ̀ wá sọ́dọ̀ rẹ lórí ọmọ kẹ́tẹ́kẹ́tẹ́, Ó sì jẹ́ onírẹ̀lẹ̀ ti O tẹnu." Bẹ́ẹ̀ ni Ó ṣe wá... lórí kẹ́tẹ́kẹ́tẹ́ kékeré kan, tí ó ru o maa nru ẹrù díẹ̀. Ṣugbọn nigbamiran ti O ba wa lati inu ogo (ni ori Ikọkandinlogun ti Ifihan), O wa bi aṣẹgun nla kan. Aṣọ Rẹ̀ ni a ri sinu ẹ̀jẹ̀, O joko lori ẹṣin funfun, gbogbo ogun ọrun si tẹle e lori ẹṣin funfun. Ati arosọ naa (kii ṣe iwe-mimọ tabi itan).… Ṣugbọn arosọ naa gbagbọ pe o gun kẹtẹkẹtẹ funfun kekere kan bi O ti ṣe wa si Jerusalẹmu.

19 Nisisinyi ti mo ti yan eyi ... o jẹ pe ... nitori pe a wa ninu awọn ojiji ti awọn ... ni akoko ti Ajọdun ti keresimesi, ati ọdun titun; òpin ọdún àtijọ́, àti ìmúṣẹ tuntun wá. Awọn ọjọ diẹ lati isisinyi, ọpọlọpọ awọn eniyan yoo yi awọn oju-iwe tuntun pada ati ṣe awọn ohun titun ati ṣiṣe awọn ẹjẹ titun; ati ti ibẹrẹ ti ọdun titun. Ati pe ko dabi keresimesi si mi. Emi ko mọ idi, mo fẹ lati pe ni Ọjọ Santa Claus nigbagbogbo." Wo? Nitoripe ko si ohun kan nipato gan….

Kò lè jẹ́ ọjọ́ ìbí Kristi. Ko le ṣeeṣe lati jẹ bẹẹ. O ni lati jẹ pe ni Oṣu Kẹta tabi Kẹrin ni a bi I, nitori pe oun ni Ọdọ-Agutan naa. Oun si jẹ akọ agutan ti a bi ni abẹ ami àgbo, (Aries). O ni lati jẹ bẹẹ, ṣe o rii. Ati pe awọn agutan kii bi ọmọ ni Oṣu Kejila botiwukori. A bi agutan ni akoko àkọ́rọ̀ ọjọ. Ohun miiran si tun ni pe, awọn òke Judea bayi, ni iwọ̀n ogun ẹsẹ bata ojo-didi lori wọn. Báwo làwọn olùṣọ́ àgùntàn ṣe lè wà níbẹ̀?

20 Nitorináà, ó wá láti inú ìtàn àròsọ àwọn ará Róòmù, ìyẹn si jẹ ọjọ́ ìbí ọlọ́run oòrùn. Gẹgẹbi Oorun ti n kọja, awọn ọjọ n gun sii lati igba de igba, ati awọn oru nkuru sii. Ati laarin ogunjọ ati ọjọ mẹẹdọgbọn ti oṣu kejila ni ọjọ ibi ọlọrun oorun, labẹ awọn itan aye atijọ ti Romu. Ati lẹyin naa awọn oriṣa wọn .... Nigbanaa Ni wọn nṣe ayẹyẹ ọjọ-ibi ọlọrun-oorun. Constantine ni igbẹkale ofin ti ijọ ati ipinlẹ ati bẹẹbẹẹ lọ. Ó sọ pé: "Àwa yóò pààrọ̀ rẹ [láìmọ̀ ohun tí ọjọ́ náà jẹ́], a ó sì fi í síbi ọjọ́ ìbí ọlọ́run oòrùn, a ó sì ṣe é ni: ọjọ́ ìbí Ọmọ Ọlọ́run," wò ó. ... ṣugbọn a ko mọ ọjọ wo ni o jẹ.

Ṣugbọn nisisiyi, nibẹ wọn ti mu Kristi kuro pupọpupọ, titi ti o jẹ ohun gbogbo ... diẹ ninu wọn mu awọn itan diẹ ti aye atijọ nipa awọn ẹda ti o gbé ri pada, awọn oloruko bi ti St Nicholas tabi Kriss Kringle, diẹ ninu awọn itan aye atijọ ti Germani. Ati pe gbogbo rẹ jẹ arosọ, Kristi ko si ninu rẹ rara.

Ati awọn eniyan ti yipada sinu ki a ra ọti oyinbo, ati ayo , ati asakasa. Ati ọkunrin kan ti o ... a oniṣowo le ta ọjà rẹ de akoko Keresimesi ti yoo si le gbe fun awọn akoko iyokù ninu odun, o ṣeeṣe, woo. O jẹ iru isinmi nla kan, iṣowo. Ati awọn talaka ọmọde lori pópó; awọn obi wọn ko ni anfaani lati bẹ wọn wo pẹlu ẹbun kan, bii lati ọdọ Santa Claus, wọn rin ni opopona, ati awọn ọwọ kekere wọn pẹlu idọti ati awọn oju wọn pupa. Mo kan korira lati rii pe o wa ṣẹlẹ bẹẹ. Ó yẹ kí ó jẹ́ ọjọ́ ìsìn ọ̀wọ̀ fún Ọlọ́run, dípò ìrora ọkàn àti ẹ̀fọ́rí àti àwọn ohun tí a ti ṣe. Ko si nkankan fun Kristi nipa iyẹn. Ṣugbọn a wa laarin gbogbo eyi ni bayi.

21 A ri ara wa, nkan bi wọn wà ṣe nigba yẹn. Wo, o n wọle ni bayi si ajọdun nla kan. Jésù ń bọ̀ wá síbi àse Ìrékọjá. O si ti wọ Jerusalemu ... tabi O nwọ Jerusalẹmu. Isọtẹlẹ gbogbo gbọdọ di mimu ṣẹ. Ohun gbogbo ti o wa ninu Bibeli ni itumọ. Orukọ kọọkan ni itumọ kan. Ko si ohun ti a kọ sinu Iwe Mimọ ṣugbọn ti ko ni itumọ ti o jinlẹ.

Mo sọ ni alẹ kan ni Tucson, lori "Kilode ti O Ni Lati Jẹ Awọn Oluṣọ-agutan Dipo Ẹlẹsin?" A bi I l'oju ijọ. Ẹ̀mí mímọ́ sì ń jáde lọ sínú aginju, ó sì gbé ẹniti kì í ṣe àwọn ẹlẹ́kọ̀ọ́ ẹ̀sìn, bíkòṣe àwọn olùṣọ́ àgùntàn. O ni lati jẹ bẹẹ. Awọn onimọ-jinlẹ kii yoo gba iru iṣẹ-iranṣẹ bẹẹ gbọ. Nitorina wọn ... o ni lati jẹ oluṣọ-agutan.

Mo wàásù níbí, ní ọdún bíi mélòó kan sẹ́yìn (ọdún méjì sẹ́yìn), "Kí nìdí tó fi jẹ́ pé Bẹ́tílẹ́hẹ́mù Kekere?" Bí Olúwa ba fẹ́, ni ọdún Kérésìmesì tí ń bọ̀, mo fẹ́ kí a wàásù lórí, "Èéṣe Tí Ó Fi Ní Láti Jẹ́ Amòye?" Àwọn "Kí nìdí" wọ̀nyí rí ìdáhùn sí wọn, wọ́n sì wà nínú Bíbélì nibi. Ati pe a n gbe ni akoko iyalẹnu, akoko nla julọ ti gbogbo ọjọ. A n gbe nigba ti, nigbakugba ni ... akoko le dẹkun ati pe ainipẹkun si le dapọ pẹlu rẹ ninu itẹsiwaju. Awọn ọjọ ti gbogbo awọn wolii ati awọn ọjọgbọn fojusọna fun…. O yẹ ki a wa nipo ẹṣọ ni gbogbo wakati wa, ki a maa ṣọna fun wiwa Rẹ.

22 A rii ara wa, ni Keresimesi yii, gẹgẹ bi wọn ti ṣe ni Keresimesi akọkọ. Aye ti mura tan lati ṣubu. Bi mo ti waasu ni ẹẹkan, nibikan, nipa iṣẹ-iranṣẹ Keresimesi kan, Aye To Nṣubu. Ati aye ti fẹrẹẹ ya pẹrẹpẹrẹ lẹẹkansi. Kiyesi awọn iwariri-ilẹ lori ibi ni California. Mo sọtẹlẹ, ṣaaju wiwa Jesu Oluwa, pe Ọlọrun yoo rìi ibẹ. Mo gbagbọ wipe Hollywood ati Los Angeles, ati awọn ibi ẹlẹgbin gbogbo nibẹ, wipe Ọlọrun Olodumare yoo rì wọn. Wọn yoo lọ si isalẹ okun. Ati pe o jẹ ẹṣẹ pupọ, o rii, o jẹ agbatẹru.

Ọlaju ti rin pẹlu oorun, lati ... o si bẹrẹ ni ila-oorun to nlọ si iwọ-oorun. Ati nisisiyi o wa ni Iwọ-oorun Iwọ-oorun. Ti o ba lọ siwaju sii, yoo pada si Ila-oorun lẹẹkansi. Bẹẹni ẹniti o ru ẹṣẹ niyẹn. Ati ẹṣẹ pẹlu ti rin pẹlu ọlaju, o si ti di ẹgbin ti gbogbo awọn igba. Awọn ohun ti wọn ṣe ti eniyan ni eyikeyi igba miiran kii yoo ronu iru nkan bẹẹ. Obirin ti ju ara wọn si iru eeri, ti ko si obinrin ni eyikeyi awọn igba ti yoo ro ti iru ohun ti a nṣe loni.

Ati pe a si tun pe ara wa kristẹni. Ẹ wo ẹ̀gàn!

23 Abajọ ti wolii nla naa fi dide, ti o si wipe, “Emi kii ṣe wolii tabi ọmọ wolii, ṣugbọn….” Wipe: Kiniun ti ke ramuramu, tani ki yoo bẹru? Ọlọrun si ti sọ̀rọ, tani le ṣe aisọtẹlẹ? (Wo, ohun kan wa ti o ni lati pe jade.)

A wa ni wakati to lagbara; aye wa nibẹ̀. Ṣùgbọ́n ìjọ, ìjọ gidi (kii ṣe ijọ-adamọ); ṣugbọn ijọ, funraarẹ, ti ṣetan fun iṣẹgun nla julọ ti o ti wa ri: wiwa ọkọ-iyawo fun iyawo.

A n wa ni apakan, a n wo fun Messia kan, ohun kan lati wa gba wa, ti yoo yọ wa kuro ninu gbogbo rẹ. A n wo ... awọn wahala ni isalẹ ni ila-oorun. A ri ni Afrika awọn rogbodiyan, ati awọn iṣoro ẹya, ati awọn ajọṣepọ, ati iyapa. Ti ede-aiyede si wa laarin gbogbo wa ti a npariwo nibi laipẹ yii (awọn ọrẹ wa alawọ dudu) nipa, “A gbọdọ ni, a gbọdọ ni ajọṣepọ. Ohun ti a nilo niyẹn. A gbọdọ ni iṣọkan; olukuluku eniyan, dọgba; gbogbo eniyan tẹriba….” Iyẹn tọ́ o si pe. Iyẹn tọ́ o si pe. Nko gbagbọ ninu ẹru. Awọn eniyan wọnyẹn kii ṣe ẹrú lati bẹrẹ pẹlu. Wọn kii ṣe ẹrú.

24 Ọlọrun jẹ olupinya. Ati Emi naa pẹlu. Eyikeyi Onigbagbọ jẹ olupinya. Ọlọ́run ya àwọn ènìyàn Rẹ̀ sọ́tọ̀ kúrò nínú gbogbo àwọn tó kù. Iyapa ti wa nigbagbogbo. O yan orilẹ-ede kan. O yan eniyan kan. O si jẹ olupinya. Ó dá gbogbo orílẹ̀-èdè. Ṣùgbọ́n síbẹ̀síbẹ̀, ojúlówó Kristẹni gbọ́dọ̀ jẹ́ oníyapa. Yiya ara rẹ kuro ninu awọn ohun ti aye ati ohun gbogbo, ki o si wa sinu eredi kan, Jesu Kristi.

Ṣugbọn wọn kigbe wipe. Mo ti gbìyànjú láti sọ fún wọn pé, “Kì í ṣe ohun tó máa gba orílẹ̀-èdè wa là niyẹn. Ilana oṣelu lasan niyẹn. O jẹ nkan ti ipilẹṣẹ ijọba dọ́gbadọ́gba.” Mo ro pe Martin Luther King yoo dari awọn eniyan rẹ sinu ipaniyan ti o tobi julọ, ati ipakupa, ti wọn ri ri. Ati pe wọn…. Ṣe o rii, iyẹn ko le fa agbaye papọ. Iyẹn kii yoo gba wa la. A fun wọn ni ajoṣepọ. Bayi o buru ju bi o ti ri lọ. Wo, iyẹn kii ṣe… iyẹn kii ṣe ibeere naa. Ohun kan ṣoṣo ni o le ṣe e: iyẹn ni Ọlọrun. Ati pe dajudaju wọn ko fẹ.

Wọn ko fẹ Ẹ nigba yẹn. Wọ́n ń ṣubú, ìṣèlú wọn sì ń wo, orílẹ̀-èdè wọn ń fọ́, ṣọ́ọ̀ṣì wọn ń fọ́, wọ́n sì ń sunkún fún Mèsáyà. Wọn fẹ Ẹ. “Ah, fi Messiah ranṣẹ si wa.” Ṣugbọn nigba ti O de....

25 Ọlọrun fun ... yoo fun ọ ni idahun si adura rẹ. O ti beere, iwọ yoo si ri gba. Ati pe iyẹn ... Mo le duro nihin fun ọ̀pọ̀ wakati, lori awọn ọkunrin ati awọn obinrin, awọn Kristẹni paapaa, ngbadura fun nkan kan; Ọlọrun si fun wọn ni idahun ti wọn ko si da a mọ.

Ati nisisiyi, Ọlọrun fun wọn ni idahun. Wọn nfẹ Messiah. Wọ́n mọ̀ pé àwọn ti ní awọn Kesari, wọ́n sì ní àwọn Dafidi, wọ́n ní awọn Solomoni (àwọn amòye), wọ́n ní Dafidi (alágbára jagunjagun), oríṣiríṣi ni wọ́n ti ní, ṣùgbọ́n wọ́n mọ̀ pé àwọn nílo láti rí ìrànlọ́wọ́ láti ọ̀run wá, wọ́n sì... Ọlọ́run si ti ṣèlérí Messiah kan fún wọn. O si rán Messiah kan si wọn, ni idahun si adura wọn, ṣugbọn wọn ko fẹ Ẹ.

26 Mo kọminu, loni, ti adura wa ba…. Ẹ gbọ ti wọn nwi pe, “Gbadura fun isọji nla. Gbadura fun eyi. Gbadura fun bibu jade. Gbàdúrà fún ìṣọ̀kan.” Mo woye pe, ti Ọlọrun yoo ba ran iru eto yii, ti a o ba gba a. Mo kan kọminu boya a o gba ohun ti O fi ranṣẹ si wa. Woo, Oun.... Idi ti a fi gbadura fun nkan wọnyi ... nitori a mọ pe a nilo rẹ ni. Ṣugbọn nigbati Ọlọrun ba fi ranṣẹ ni ọna ti o fẹ, nigbanaa kii ṣe gẹgẹ bi itọwo wa, nitorina a ko ni gba a. Bẹ́ẹ̀ sì ni ó rí ní ọjọ́ yẹn. Bi ko ba ba adun igbagbọ wọn mu, ati ti wọn.... Wọn ko ni gba A, loni. Ìdí nìyí tí wọ́n fi bèèrè ìbéèrè yìí pé, “Tani èyí? Tani ẹni tí ń bọ̀ yìí?” Wo, o jẹ akoko nla kan. Oh, gbogbo eniyan ni ... aya ko balẹ. Nkankan n ṣetan lati ṣẹlẹ.

27 Ki o si wo aye loni, iru wahala ti gbogbo agbaye n wa ninu rẹ. Ti o ba lọ si ita l'oju popo ... O jẹ ewu lati wakọ. Ewu ni lati wa ni oju opopona mẹrin. Gbogbo eniyan wa ninu wahala, imọlara ati .... Kini o ṣẹlẹ? Dakẹjẹẹ. Nibo ni iwọ nlọ? Iyẹn ni o jẹ ki awọn ile-itọju aṣiwere kun fọ́fọ́. Ohun ti o mu ki ijọ wa ninu iru rudurudu niyẹn. Wọn ti di olori-kunkun lori ohun kan. Wọn ko ni duro ati ro Ọrọ Ọlọrun, ati wakati ti a n gbe; gbogbo eniyan wa labẹ inira, aibalẹ aya.

28 Ati nisisiyi, a mọ. O ye wa. Ilẹ̀ ayé ṣẹ̀ṣẹ̀ la ìrora ìbímọ ńlá kan kọjá. Ati pe ijọ ti nla awọn irora ibi kọja. Ó ní láti la ìrora ìbímọ ja kí ó tó lè fúnni….. Olúkúlùkù àwọn wòlíì, nígbà tí wọ́n wá sí ayé, ìrora ìbímọ ni fún ìjọ. Aye ti kọja Ogun Agbaye akọkọ, Ogun Agbaye Keji, ati ni bayi o ti ṣetan fun Ogun Agbaye Kẹta. Ati pe o tun wa ninu irora ibimọ lẹẹkansi. Ṣugbọn ohun kan ṣoṣo ni o wa ti o le mu alaafia wá, iyẹn ni Kristi.

Gbogbo awọn eto wa, ati awọn ero wa, ati awọn ile ijọsin wa, ati gbogbo iṣelu wa, ati gbogbo imọ-jinlẹ wa ati gbogbo nkan, a ti fi idi rẹ mulẹ pe isọkusọ ni. Ati lẹyin naa a gbadura fun Ọlọrun lati ran wa lọwọ, lati dasii, “Wọle wa ki o ṣe ohun kan fun wa.” Ati lẹyin naa nigbati O ba ṣe, Mo kọminu boya a o ni anfaani lati loye rẹ; bí a bá lè gbà á; tabi paapaa awa yoo ronu nipa rẹ?

29 Bayi, ohun ti wọn ṣe nigba atijọ niyẹn. Wọn ti ngbadura, wọn ni oniruuru awọn adari nla, wọn ti wa labẹ ijọba, wọn wa labẹ ọba, wọn ti wa labẹ ohun gbogbo, awọn onidajọ. Ṣùgbọ́n wọ́n mọ̀ pé ohun kan ṣoṣo ló wà tó lè gbà wọn là, ìyẹn ni Mèsáyà tó ń bọ. Mèsáyà náà sì túmọ̀ sí “ẹni àmì òróró náà.” Ènìyàn kan tí a fi àmì

òróró yàn. Nigbana ẹda eniyan naa, ni àmì òróró Ọrọ yàn. Ọrọ naa di ara laarin wa. Ati nigbati O si de, ko wa ninu adun ti wọn le fi fẹ Ẹ; Kì í ṣe adùn tí wọ́n ní... pé kí ó wọlé. Nítorí náà wọ́n kígbe pé, “Ta nìyí? Kini gbogbo racket yii nipa?” Àwọn ẹgbẹ talaka lasan kan wa lẹ́nu ibodè, wọ́n ń ja ọpẹ́ àti....

O si wipe, eeṣe, mu ki wọn pa ẹnu wọn mọ́. Wọ́n ń kó jìnnìjìnnì bá wa, bí wọ́n ṣe ń pariwo, tí wọ́n sì ń kigbe, ati bẹẹbẹẹ lọ.“

Ó ní, “Bí wọ́n bá pa ẹnu wọn mọ́, àwọn àpáta wọ̀nyí yóò kígbe lẹsẹkẹsẹ.”

30 Oh, akoko ti n ṣii silẹ! Àsọtẹ́lẹ̀ ti ń di ìmúṣẹ. Abajọ! “Kìnnìún ké ramúramù.” Ó ní, “Tani kì yóò bẹ̀rù? Ọlọ́run sì ti sọ̀rọ̀, tani si lè ṣe aisọtẹ́lẹ̀?”

“Rara, ti ko ba jẹ ninu adun itọwo tiwa …. Ti ko ba jẹ ọna ti a fẹ Ẹ nikan, ọna ti a ro pe o yẹ ki Ó wá, àwa kò ní gbà Á.” Nigba naa awọn igbagbọ wọn ni o mu wọn kuro ninu Ọrọ ti a ti kọ. Wọ́n jìnnà rere, wọ́n kùnà láti mọ ẹni tí wọ́n ti gbàdúrà fun pé kí ó wá. Àwọn ìjọ wọn ti mu wọn jìnnà réré sí, títí di ìgbà tí ohun tí wọ́n ti gbàdúrà fún, fi tọ̀ wọ́n wa, kò sì sí nínú adun wọn, nítorí náà wọn kò lè gbà á gbọ́. Wọn ni lati lọ kuro ninu rẹ. Wọn lé E kúrò. Ohun kan ṣoṣo ni o le ṣe nigbati o ba pade Kristi. Boya ki o gba A tabi kọ Ọ. O ko le rin kuro lasan. O ko le ṣe bẹ. Kii ṣe fun ọ lati ṣee. Bi o ṣe jẹ yẹn.

31 Ṣe akiyesi, bi awọn diẹ ṣe mọ pe Oun ni Ọrọ tii ṣe ẹni-ami-ororo naa, ti ọjọ yẹn. Kiyesi i, Ọlọrun li atetekọṣe, ti o jẹ ailopin, ti O si mọ ohun gbogbo lati ipilẹṣẹ…. Ati ohun kan ti nkan wọnyi jẹ ni ifihan awọn iwa ẹda Rẹ. Iwa kan…. O ni iwa ẹda kan. O jẹ ero rẹ. O ronu nkan kan, lẹyin naa o sọ, lẹyin naa o mu. Ọlọrun niyẹn. Oun, ni ibẹrẹ .... Ti o ba .... Ti o ba wa tabi iwọ yoo ba wa ni ọrun, o wa ni ọrun lati bẹrẹ pẹlu. O jẹ apakan ti Ọlọrun. O jẹ ero Rẹ̀. O mọ orukọ rẹ. O mọ ẹni ti o jẹ ṣaaju ki moleku to wa, ṣaaju ki imọlẹ to wa. Ṣaaju ki ohunkohun to wa, O mọ ọ ati orukọ rẹ. O sì fi i sinu ìwé ìyè Ọ̀dọ́ Àgùntàn náà, kí a tó dá ayé. Kiyesi i, iwọ ni ero Rẹ. Ati lẹyin naa o di ọrọ kan. Ati pe ọrọ jẹ ero ti a sọ. Lẹhin eyi ni o farahan.

32 Bi o ti ri niyẹn. Òun wà ní ìbẹ̀rẹ̀ fúnrarẹ̀. Ọlọrun n gbe pẹlu ero Rẹ fúnrarẹ̀. Oun ki yoo tun ṣe bẹẹ mo nitori a nfi ero Rẹ han. Ìdí nìyí tí a fi wà níhìn-ín, lónìí... Ọlọrun nba ero Rẹ ti a fi han ni idapọ. Woo? Nibẹ ni a wa. Nítorí náà, ìwọ, nípa ríronú, kò lè fi ìgbọ̀nwọ́ kan kún gigun rẹ. O ko le ṣe eyi, iyẹn, tabi omiran. Ọlọrun lo n ṣe aanu. Ọlọrun ni. “Gbogbo awọn ti Baba ti fifun mi ni yoo wa si ọdọ mi, ko si si ẹnikan ti o le wa ayafi bi Baba mi ba fa a.” Iyẹn yanju rẹ.

33 Nísisìnyí, sakíyèsíi, bí ìwọ̀nba díẹ̀ nínú wọn ní ọjọ́ Rẹ̀, nínú àwọn ọ̀pọ̀ ọ̀kẹ́ (miliọnu) ènìyàn lórí ilẹ̀ ayé, tí kò tilẹ̀ mọ̀ nípa wíwà Rẹ níhìn-ín rí. Jọwọ ronu, awọn mẹwa… awọn ọ̀pọ̀ ọ̀kẹ́ (miliọnu) eniyan ti ko mọ nkankan nipa rẹ rara. Àti láti ronú, ní Israẹli nígbà yẹn, mílíọ̀nù méjì àtààbọ̀ ènìyàn ló wà ní Palestine, lára àwọn ọmọ Israẹli, kò sì to idakan ninu ọgọ́rùn-ún nínú wọn tó mọ̀ nipa rẹ. Abájọ tí Ó fi sọ pé, “Hiha ni ẹnubodè náà, tóóró sì ni ojú ọ̀nà naa, ṣùgbọ́n díẹ̀ ni yóò rí.” Sa ronu nipa melomelo eniyan ti ko da a mọ! Ti ko mọ pe Oun ni iyẹn. Ti wọn si wa ni ayika ibi ti o wà ni; iyẹn jẹ ohun ti o ṣeni laanu.

Àwọn tí wọ́n bá A rìn, tí wọ́n sì rí I ní òpópónà, àti bẹ̀ẹ̀ bẹ̀ẹ̀ lọ.. wọn ko da Ohun ti o jẹ mọ, nitoripe Satani ri pe O ni orukọ ti o buru jai ti wọn le fifun eniyan. Ayé ló pè E ni (aye ti ara) … wọn pe E ni ọmọ ale (nitoripe iya Rẹ ti loyun Rẹ ki o to fẹ Joseph). Nitorina wọn fun Un ni orukọ aitọ.

34 Àti lẹ́ẹ̀kan sí i, ìjọ rí i nínú agbára ńlá rẹ̀ ti ìfarahàn. O nfi kini han? Koṣe afihan ẹkọ́-igbagbọ kan! O nfi Ọrọ naa han! Oun ni Ọrọ-to ni ami-ororo naa, funra Rẹ. Nígbà tí wọ́n sì rí i pé ó ń ṣẹlẹ̀, ìfarahàn náà, Mèsáyà ẹni àmì òróró, wọ́n kọ̀ ọ́. Wọn ko fẹ. Ko si ni itọwo wọn. Iyẹn ṣeni laanu. Bawo ni ọpọlọpọ .... Kan ronu rẹ! Gẹgẹ bi i awọn ọjọ miiran.

Wo, ikọọkan ní itumọ ti ara wọn ti Ọrọ naa. Ìdí nìyí tí Israẹli kò fi mọ Mósè. Ìdí nìyẹn tí ayé kò fi dá Nóà mọ́. Ìdí nìyẹn tí wọn kò fi mọ̀ gbogbo àwọn wòlíì náà. Wọn ni itumọ tiwọn ti Ọrọ naa. Ṣugbọn Ọlọrun, ni gbogbo igba, ti ni Messia ti Rẹ. Lati kọ iṣẹ-iranṣẹ Noa, ni lati kọ Ọlọrun silẹ. Lati kọ Noa, ni lati ṣegbe. Lati kọ Mose, ni lati ṣegbe. Ó jẹ́....Wọ́n jẹ́ Messia ẹni-àmì-òróró fún àkókò yẹn, Ọ̀rọ̀ tí a ṣèlérí fún àkókò náà. Ati nigbati Jesu de, Oun ni ẹkun ti Ọrọ naa.

Ọlọrun, tikararẹ, ti a ṣe si ẹda eniyan, pẹlu egungun ati ẹran ara; ẹni àmì òróró naa. Ati pe o yẹ ki wọn ti rii iyẹn. Ṣùgbọ́n ẹ rí i, ìjọ-ayé wọn ti fi kún un níhìn-ín tí wọ́n sì ti yọ kuro níhìn-ín àti bẹ̀ẹ̀ bẹ̀ẹ̀ lọ, títí tí ó fi dàrú bẹ̀ẹ̀ títí tí wọ́n fi gbẹ́kẹ̀ lé ìjọ wọn dípò Ọ̀rọ̀ náà. Nígbà tí wọ́n sì rí i ijọ wọ́n pẹlu àmì òróró, wọ́n rò pé ohun ńlá kan ń ṣẹlẹ̀. Ṣùgbọ́n nígbà tí wọ́n rí Ọ̀rọ̀ náà tí a fi àmì òróró yàn, nígbà náà ni wọ́n wí pé, “Ìyẹn ni gbigbawèrè mọ ẹsin. Bìlísì ni ọkùnrin yìí, Béélísébúbù ni.” Nitoripe o lodi si ile ijọsin wọn titi di ... awọn igbagbọ ijọ wọn ati ohun ti wọn ti ṣe. Ati pe bi o ti ṣe ri niyẹn ni gbogbo igba wiwa wolii kan, ijọ yoo ti daru.

35 Ọlọ́run rán àwọn òfin Rẹ̀ jade, Ó sì fún wọn ní májẹ̀mú kan. Àwọn alufaa a sì wọlé, wọn a sì gé kúrò, wọn a sì fi kún un, wọn a sì gbà níhìn-ín, wọn a sì fi í ṣe ẹkọ́ ijọ. Nígbà náà, ni Ọlọ́run yóò gbé àwọn ẹni àmì òróró kan dìde laini ibi kankan, tí a gbe dìde nínú agbára Ẹ̀mí. Ati pe awọn alufa, ati awọn ọba a maa korira rẹ

nigbagbogbo. Ati nibiti awọn wolii eke ti wọ aṣọ fẹlẹfẹlẹ wọn, ti wọn si rin ni irẹlẹ, ati ni irọra laarin awọn ọba ati awọn alufa, lati yẹ fun awọn orukọ nla ati awọn ohun kan. Lẹyin naa wolii gidi nitootọ, jade wa lati ibi kan, ti kii si ṣe lati inu ọkan ninu awọn eto-ijọ wọn.

Nibo ninu Bibeli, ni Ọlọ́run ti mu alufaa kan ti o si sọ ọ́ di wolii rí? Ibo ni Ọlọ́run ti mú ẹlẹ́kọ̀ọ́ ẹsìn ṣọ́ọ̀ṣì kan rí (ọkùnrin tó ti a kọ lẹ́kọ̀ọ́, ọkùnrin tó ti kẹ́kọ̀ọ́ ẹsìn) tí ó sì fi ṣe wòlíì kan ri? Ko si ninu awọn itan ti nibikibi, ti O ṣe e ri, ni eyikeyi akoko... Ko ti ṣe ri. O ni lati lọ kuro ninu eto naa, ki o si mu jade wa. Ohun tí Ó sì ṣe níbí nìyẹn.

36 Jesu, nigba ti a bi ni Bẹtlẹhẹmu ti Judea, lati inu idile talaka, ko si ni ipilẹṣẹ bi wọn ti ṣe mọ, ọkan kan ninu ẹya Juda, ati iya ati baba rẹ lati idile Dafidi; nwọn si ni lati goke wa fun eto ikaniyan ti owo-ori sisan. O si wà nidi, O kan jẹ ọdọ kan, ni ayika ... Ko ṣe ohun kan bikoṣe fifa awọn ijọ ya. Nwọn si korira Rẹ. Ati pe wọn ko le sọ ohunkohun bikoṣepe ọkunrin yẹn ṣe awọn iṣẹ iyanu. Pétérù sọ nipa iyẹn ní ọjọ́ Pẹ́ńtíkọ́sì, ó sọ pé: “Jésù ará Násárétì, ọkùnrin kan tí Ọlọ́run fọwọ́ sí láárín wa, pé Ọlọ́run wà pẹ̀lú Rẹ̀.” Ati pe ki n maṣe fi kun Ọrọ Rẹ tabi ohunkohun; ṣugbon láti sọ alaye díẹ̀ : “Ó jẹ́ Ọlọrun ti o di ara pẹ̀lú wa. Ọlọrun wa pẹlu wa.”

37 Mo si wi ni alẹ ọjọ́ kan pe, Mose, duro nibẹ̀ ti oun ti ọwọ́ rẹ̀ ni aya rẹ̀, iyẹn ni Ọlọrun ninu Mose ti o di aṣiri mọ́ ọkàn rẹ̀, o si di funfun pẹlu ẹ̀tẹ̀. Nigbana ni o fa pada si aya rẹ, o si mu u larada, o si tun naa si wa nigbati o rán Ẹmí Mimọ sọkalẹ; tí ó jẹ́ Ọlọ́run, lẹ́ẹ̀kan sí i, ní ìrísí mìíràn ní ọjọ́ Pẹ́ńtíkọ́sì. Ati pe a kọ silẹ. A ko fẹ iyẹn. Bí wọ́n ṣe ṣe nígbà náà nìyẹn. Iyẹn ni ọna ti a ṣee ṣe loni.

38 A rii, olukuluku ni itumọ tirẹ. Idi ti o fi ruju niyẹn. Ṣugbọn o mọ, Bibeli wi pe, Ọrọ yii ko ni itumọ ikọkọ. Ko nilo itumọ ijọ awọn Alagba fun. Ko nilo itumọ Onitẹbọmi kan. Bẹẹni ko nilo itumọ afedefọ kan. Ọlọrun ni olutumọ ara Rẹ. O ni Oun yoo ṣe e, nitori naa Oun si ṣe e, iyẹn si yanju rẹ. Ìdí nìyí tí wọ́n fi rí ẹni àmì òróró Ọ̀rọ̀ ìlérí tí wọn kò sì lè gbà á. Ṣe o rii, nitori pe o lodi si awọn igbagbọ wọn.

39 Bi Mèsáyà, ẹni àmì òróró, yóò ṣe rí, àti ohun tí yóò ṣe; ó jìnnà sí òye wọn. Ati lẹyin nigba ti a ka a fun wọn lati inu Iwe Mimọ, ohun ti yoo ṣe, sibẹsibẹ wọn ko loye rẹ. Nítorí nígbà tí àwọn amòye wọnyi sọ̀kalẹ̀ wá, láti Babiloni, wọ́n wa lati àríwá ìlà oòrùn Jerusalẹmu, wọ́n bojú wolẹ̀, wọ́n sì rí ìràwọ̀ tí ó ń lọ sí ìhà ìwọ̀-oòrùn. Wọ́n tẹ̀lé e fún ọdún meji, wọ́n ń sọ̀ kalẹ̀ ní Odò Tigirisi, ati àwọn àfonífojì ati Ṣinari, wọ́n sì gòkè wá; wa si ilu olori gbogbo awọn ẹsin. Ẹsin ti o tobi julọ ni agbaye, ninu tẹmpili, ni Jerusalemu. Ati si oke ati isalẹ awọn oju popo wọn nwipe, “Nibo ni O wa? Níbo ni ẹni tí a bí ní ọba àwọn Júù gbe wa?” Kilode, ko si ẹnikan ti o mọ nkankan nipa rẹ. O jẹ ajeji.

40 Ó tiẹ̀ rú ìgbìmọ̀ Sànhẹ́dírìn soke . . . Wọn pe àwọn ọ̀mọ̀wé jáde, wọ́n sì sọ pé, “Ẹ wa ínú Ìwé Mímọ́ níbi tí Mèsáyà ti wà...”

Wọ́n sì lọ gba Ìwé Mímọ́, wọ́n sì kà pé Míkà sọ pé “Lati inu… Jùdíà... Bẹ́tílẹ́hẹ́mù ti Jùdíà, ìwọ kò ha kéré jù nínú gbogbo àwọn ọmọ alade? Ṣùgbọ́n láti inú rẹ ni gómìnà yìí yóò ti jáde wá.”

Wo, dipo iwadi, wọn kan sọ ọ silẹ, “O jẹ ọpọ igbawere mẹsin,” wo. Ìdí nìyẹn tí àwọn olùṣọ́ àgùntàn fi gba iṣẹ́ náà. Wo, wọn ko .... Wọn ni itumọ tiwọn, nitorina, wọn padanu ohun otitọ gidi naa.

41 Ṣùgbọ́n gẹ́gẹ́ bí ìgbà kan rí, nígbà tí ó dé, ó wa ni ibamu gẹ́gẹ́ bí Ọ̀rọ̀ náà ti sọ pé yóò wá. O wa sinu ilu ni pato, ninu ọrọ wa ni owurọ yi, ọna ti Ọrọ ti sọ pe Oun yoo wa. Nwọn si wipe, Tani eyi? Ṣe o ri ohun ti mo n sọ? Ó yẹ kí wọ́n mọ ẹni tó jẹ́. Ati nihin... kii ṣe aye nita, ṣugbọn ijọ sọ pe, “Tani eyi? Tani eyi?” nigba ti, nibẹ, Iwe Mimọ ti sọ ni gbangba pe iyẹn gan-an ni ọna ti yoo fi wa. Wọ́n sì wí pé, “Ta ni eyi? Tani ẹni yii? Kini gbogbo imọlara yii jẹ? Da gbogbo ariwo yẹn duro. O mu wa ni aifọkanbalẹ,” wo. Ohun náà gan-an tí wọ́n ti gbàdúrà fún wà ní ọwọ́ wọn gan-an, wọn kò sì mọ̀ Ọ́. Ó sì wá gan-an gẹ́gẹ́ bí Ìwé Mímọ́ ṣe sọ pé yóò wá. Bi O ba si ṣe eyi loni, Oun yoo wa gẹgẹ bi Iwe-mimọ ti wi pe yoo wa. Ó máa ń wá nínú ìtọwo Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run, kì í sì í ṣe ninú adun àwọn ẹlẹ́kọ́ ẹsìn kankan nípa rẹ̀.

42 Nípa bẹ́ẹ̀, ǹjẹ́ o mọ̀ pé Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run kò wa lati ọ̀dọ̀ ẹlẹ́kọ́-ẹsìn rí? Wa awọn Iwe Mimọ nibiti o ti ṣẹlẹ ri. Ọrọ naa kii wa sọdọ awọn onimọ-jinlẹ ẹsin; rara. Ṣùgbọ́n ẹ rí i pé, bí a bá fi Ọ̀rọ̀ náà hàn lóní, Ọ̀rọ̀ náà fún ọjọ́ wa, yoo jẹ́ nínú adun Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run. Ko si ni jẹ ninu itọwo ti ero ẹnikan. Ọlọ́run yóò gba Ọ̀rọ̀ Rẹ̀ tí Ó ṣèlérí fún ọjọ́ òní, yóò sì fi òróró yàn án, yóò sì ṣẹlẹ̀. Gbogbo rẹ niyẹn. Ko si ọna lati jẹ ki o ma ṣẹlẹ. Yoo ṣe bẹ lọnakọna, laibikita ohun ti ijọ sọ ati ohun ti awọn iyokù wọn gbagbọ. Ọlọrun yoo ṣe e lọnakọna. Awọn diẹ diẹ ni yoo wa ti yoo mọ nipa rẹ. Otitọ ni, diẹ ni yoo jẹ. Bi o ṣe nri nigbagbogbo niyẹn.

43 Wò ó, pẹ̀lú ìtumọ̀ tiwọn, wọn kò lè ṣe nǹkan mìíràn nítorí pé wọ́n gbára lé ohun tí ìjọ ti sọ fún wọn. Ṣugbọn Oun yoo wa ... O maa nwa nigba nigbagbogbo... O ṣe bẹẹ, ati pe Oun yoo ṣe bẹ ni gbogbo igba ti O ba wa, gbogbo ohun t'O nṣe, yoo wa ninu adun Ọrọ naa. Nitorinaa, a ko le ni igbẹkẹle ninu ohun ti awọn eniyan miiran sọ. Ohun kan ṣoṣo ni o wa ti o le fi igbẹkẹle si, ati pe iyẹn ni Ọrọ naa. Ọlọrun si ni Ọrọ na. Ọ̀rọ̀ náà tí a fi àmì òróró yàn sì ni Mèsáyà náà; Ọ̀rọ̀ ti a fi ami ororo yan fun wakati naa. O ti lẹwa to! Wọn padanu

rẹ, Ọrọ naa; bẹẹni .... Wọn ni .... Ọrọ naa jẹ otitọ nigbagbogbo, ṣugbọn itumọ wọn ni ko tọ́.

44 O yamilẹnu boya ohun nla yii, Igbimọ ijọ nla yii ti a ni ni agbaye loni, ati Igbimọ Agbaye ti Awọn ile ijọsin ti wọn ko papọ ṣ'ọkan… O yamilẹnu boya wọn mọ boya iyẹn gan-an ni ohun ti Iwe Mimọ sọ pe wọn yoo ṣe. Ṣugbọn wọn ro pe o jẹ ohun iyanu julọ ni agbaye, pe gbogbo wa le so ọwọ pọ lati jẹ ọkan. Wọn sọ pé, “Jésù gbàdúrà kí a lè jẹ́ ọ̀kan.” Ootọ niyẹn. Ṣugbọn kii ṣe iru isọkan yii.

Ó sọ pé, “Ẹ jẹ́ ọ̀kan gẹ́gẹ́ bí èmi àti Baba ti jẹ́ ọ̀kan.” Bẹẹni, jẹ iru ọkan yẹn. Nigba naa bawo ni iyẹn yoo ṣe ri? Ọrọ naa ati awa yoo jẹ Ọrọ-ẹni-ami-ororo. Isọkan Ọlọrun niyẹn. Ẹ wò ó, ìṣọ̀kan Ọlọrun ni Ọ̀rọ̀ tí a fi òróró yàn ninu yín, ẹ wò ó. Ati lẹyin naa wa di ọmọ, Messia kan, fun ọjọ-oni.

45 Bayi a ri awọn eniyan pe bakanna ni wọn. Awọn eniyan ko yipada. Awọn eniyan wọnyi pin si awọn ẹgbẹ mẹta. Ati pe a o si wo iyẹn fun iṣẹju diẹ bayi. Mo mọ pe Emi yoo pẹ diẹ, ti o ba dara bẹ pẹlu yin. Mo lọra pupọ, Mo kan…. Emi ko mọ; Mo wọle ati kọ Iwe Mimọ silẹ, ati awọn akọsilẹ kekere. Ati pe nigbati mo de ibẹ Ẹmí Mimọ si gba akoso ọkan, ati ki o Mo ... o si wa da bi pe ko si opin si. O kan ntẹsiwaju lọ. ṣugbọn, ni bayi, si ọrọ wa.

46 Wọn pin, nibẹ, si awọn ẹgbẹ oriṣiriṣi mẹta, pẹlu awọn ero oriṣiriṣi mẹta. Diẹ ninu wọn gba A gbọ. Diẹ ninu wọn korira Rẹ. Diẹ ninu wọn ko mọ ohun ti wọn yoo ṣe.

Wo, iyẹn ni ọna ti a gba a. Mo waasu rii, mo gbagbọ pe ninu ijọ yii, ni ẹẹkan ri: awọn onigbagbọ, awọn alafẹnujẹ-onigbagbọ, ati awọn alaigbagbọ. Awọn mẹta yi wa ninu ẹgbẹ, nibi gbogbo. Eyi jẹ mẹta ti o wa ninu ẹgbẹ, paapaa; a ri pe ipo awọn eniyan ni nigbagbogbo. A le pada sẹhin lati jẹri, iyẹn ni ipo awọn eniyan nigbagbogbo. Wọn ti wa ni iru ipo yẹn nigbagbogbo.

Lẹ́yìn náà ti a rí i pé bẹ́ẹ̀ ló máa ń rí, ó máa jẹ́ ká gbà pé Ọlọ́run dá àwọn èniyàn láti rí bẹ́ẹ̀. Eeṣe, Yoo mu ọta Rẹ yin In. Ohun gbogbo ... Paulu, kọ, ninu iwe Romu ori kẹjo, wipe, “Ah, aṣiwere eniyan. Amọ le wi fun amọkoko pe, eeṣe ti O fi ṣe mi bẹẹ? Ǹjẹ́n kò ha ní agbára láti sọ ohun èlò kan fún ọlá, àti òmíràn sí ailọlá?” Ti ko ba ṣe òru nkọ? Iwọ ko ni mo riri oorun. Ti gbogbo rẹ ba jẹ oorun, iwọ kii yoo mọ bi o ṣe le mọ riri rẹ. Ti ko ba si aisan nkọ? Iwọ kii yoo mọ bi o ṣe le mọ riri ilera to dara. Ti ko ba si eniyan buburu nkọ? Ti ko ba si obinrin buburu? Obinrin rere ko ni lọla, wo. Ọla kii yoo jẹ tirẹ, nitori pe bi o ti ri niyẹn, ọna kan ni gbogbo rẹ, ohun kanṣoṣo ni. Ṣugbọn o jẹ ofin awọn iyatọ.

47 Ọlọ́run lo ṣe e bẹ́ẹ̀: Ọkan lati jẹ́ ailọ́la, láti fi eyi tí ó ní ọlá hàn; ọkan lati jẹ aṣiṣe pupọ, o fihan…. Ti kii ba ṣe bẹẹ, iyẹn yoo jẹ ohun ti o tọ. Ti ko ba si.... Ko le si ayederu dọla kan titi ti dọla gidi yoo fi wa. Ati pe awọn ayederu ni.... Ti o ba kan jẹ ayederu ni lati ibẹrẹ, a jẹ wipe oun ni ojulowo. Ṣugbọn o jẹ ẹ̀dà kan. Ko le si... ẹṣẹ ko le wa titi ododo yoo fi wa. Nitori ododo ni ohun ti o tọ, ati ẹṣẹ ni alupayida ododo. Ni ọrọ miiran, otitọ jẹ otitọ. Irọ ko le jẹ irọ titi otitọ yoo kọkọ wa; láti yí òtítọ́ yẹn padà sí irọ́. Nítorí náà, gbogbo ẹṣẹ ko jẹ nkankan bikoṣe ayipada ododo. Nitorina, eto kan wa ni agbaye.

48 Awọn eto meji; ati pe ọkan ninu wọn ni eto ti o tọ, ati ekeji si jẹ eto ayipo. Ati ọkan ninu wọn ni Ọrọ Ọlọrun, eyi ti o tọ́; irọ́ sì ni ọ̀rọ̀ gbogbo èniyàn. Ati pe eto ẹsin yii ti a ni loni, ti wọn nṣe Igbimọ Awọn Ijọ ti Agbaye lati ṣe ami ẹranko lati da wọn papọ, jẹ ohun ti ko tọ. Ati pe awọn eniyan ti rin ninu rẹ nipa ifọju.

Ọlọ́run ti ṣe ohun náà sínu ayé kí wọ́n lè rí ìgbàlà. Ṣugbọn wọn ro pe o jẹ gba-were-mẹsin ni. Wọn ko fẹ. Wọn le e jade. Wọn ro pe wọn ni lati ṣe nkankan nipa rẹ. Wọn ni lati ṣe eto ti ara wọn. Ọlọrun ti ni eto tẹlẹ nibi, Ọrọ Rẹ. Ṣugbọn a ko fẹ iyẹn. Nitorinaa a ri ara wa loni, gẹgẹ bi wọn ti jẹ nigbana.

49 Bayi, a ri pe a ti da eniyan lati wa ni ọna yẹn ... kiyesi, o sọ ... Mo mọ pe mo ti gba ọpọ akoko, ṣugbọn emi ko fẹ lati maa wo agogo yẹn nitori o mu mi wa ni aifọkanbalẹ, wo.

Oṣelu; bayi a .... Jẹ ká kan ya fun apẹẹrẹ ... ri ti a ba da eniyan lati wa ni egbe mẹta. Jẹ ki a mu oṣelu. Awọn diẹ wa ti wọn gbona lala fun ọkunrin kan. Ati ẹgbẹ miiran korira rẹ. Ati ẹgbẹ miiran ko mọ ohun lati ṣe nipa rẹ; wọn kò mọ èwo, ó sì sọ wọ́n sínú ìdàrúdàpọ̀.

Ọkunrin yii sọ pe, “Ah, ọkunrin nla ni. Oun yoo jẹ Aarẹ ti o dara julọ fun wa. ”

Ekeji sọ pe, “Kii ṣe nkankan bikoṣe ọlọtẹ.”

Lẹyin naa ẹni ti o wa laarin sọ pe, “Nisisiyi Emi ko mọ ohun ti n o ṣe.” Wo, a ṣe wa ni ọna yẹn. A ṣe wa ni ọna yẹn. Bi eniyan ṣe ri niyẹn. O ni lati jẹ bẹyẹn lati mu ọrọ-aje nla Ọlọrun ṣẹ. Ati lati mu aṣeyọri Rẹ ti O fẹ ṣe lori ilẹ aye ṣẹ, O nilati ṣe eniyan ni lati bayi. Ọkan jẹ titọ. Ekeji jẹ aṣiṣe. Ati omiiran laarin awọn mejeeji. O ti nri bẹẹ nigbagbogbo.

50 Kiyesii, wọn ṣe bẹẹ ni igba gbogbo wọn ko si mọ…. Ọkunrin ti o wa laarin, ibi buburu lo wa nitoripe: eniyan le fi ọran naa han, ki o ro pe oun tọ; ekeji le fi idi ti o ro pe o fi kuna han; ẹniti o si wa laarin ko mọ

nkankan nipa ọrọ naa, ko mọ ọna ti yoo koju si. Bí ó sì ṣe rí nínú ẹ̀sìn nìyẹn. Awọn eniyan n ṣe ohun kanna loni nipa opin-ajo ayeraye wọn.

Ni bayi a o pa wa lara, fun iṣẹju kan. Wọn ṣee nipa opin-ajo ayeraye wọn. Ọkunrin kan yoo sọkalẹ lọ si ... nibiyi ... lati jẹun. Ati pe ti o ba rii alantakun ninu ọbẹ rẹ, iwọ yoo fẹ lati pe ile-iṣẹ yẹn tabi ile ounjẹ yẹn lẹjo. Kilode, o ko ni jẹ ọbẹ yẹn, majele ni yoo jẹ. Iwọ kii yoo gba rara, alantakun nla kan tabi ohun kan ti a fi sinu awo ọbẹ kan. Kilode, iwọ kii yoo gba a rara. Yoo jẹ ki o ṣaisan lati ronu nipa rẹ. Ṣugbọn sibẹsibẹ, iwọ yoo jẹ ki awọn onimọ-jinlẹ tẹ ohun kan si ọfun rẹ ti yoo ran ọ ni awọn ibusọ miliọnu kuro lọdọ Ọlọrun, ti wọn yoo si bori rẹ. Nigbati "Eniyan yoo wa laaye nipa gbogbo Ọrọ ti o ti ẹnu Ọlọrun jade." O jẹ ẹwọn ti o so ọkan rẹ lori apaadi pẹlu. Ati gẹgẹ bi mo ti sọ tẹlẹ, "Ẹwọn kan ko dara ju ibi alailagbara rẹ lọ." Ibi asopọ kan lati ja ... gbogbo ohun ti o ni lati ṣe ni lati ja ọkan ninu wọn; gbogbo rẹ niyẹn. Awọn iyokù ni yoo si ja pẹlu rẹ. O lagbara nikan ni ibi ọna asopọ alailagbara rẹ.

51 Bayi....Eniyan ti o si mọ pe bi oun ba jẹ ọbẹ yẹn pẹlu majele alantakun ninu rẹ, o ṣeeṣe ki o ṣe aisan. Iwọ yoo ni lati lọ si ile-iwosan, ki o jẹ ki wọn fa a jade lati inu ikun rẹ ati wahala pupọ lati la kọja. Ati pe o le pa ọ gan-an. Ṣugbọn, ah! O fẹ…. Kilode, iwọ ko ni lọ si ayika agbegbe bii iyẹn rara. Iwọ kii yoo fẹ lati tun ṣe ilẹkun yẹn mọ ara rẹ lẹẹkansi, nitori o maa bẹru pe iwọ yoo jẹ majele ti yoo si pa o. Ṣugbọn iwọ yoo darapọ patapata mọ, fi orukọ rẹ sinu awọn iwe, ki o si ja fun idi ohun ti Bibeli sọ pe, "Kii ṣe pe o ba ara rẹ jẹ, ṣugbọn o fi ẹmi rẹ ranṣẹ si ọrun apadi." Wo? Bawo ni eniyan ṣe ohun ajeji. Wọn gbe opin irin ajo ayeraye wọn, lori awọn ọrọ ẹkọ ẹsin kan. Ẹ sì lè mú Ìwé Mímọ́ wá fún wọn pé, "Èyí ni ohun tí Bíbélì sọ. Nibi ni o gbe wa."

Ati pe awọn onimọ-ẹsin wo o, "O dara, iyẹn wà fun ọjọ miran," wo. Ati pe iwọ si gbọ tirẹ. O si ri ohun ti Ọlọrun sọ. Onigbagbọ otitọ ngbọ Ọrọ yẹn nikan, iyẹn nikan. Àwọn ènìyàn Ọlọ́run ń gbé nípa oúnjẹ náà.

52 Kiyesi, diẹ ninu wọn gbagbọ ninu Ọrọ naa. Nigba ti awọn miiran wa to gbagbọ ninu itumọ ijọ adamọ̀ wọn. Ati pe awọn miiran wa, nipasẹ rudurudu yii, ti ko mọ ohun kan lati gbagbọ.

Nísisìyí àwọn kan nínú wọn wípé, "Oh, Ìgbìmọ̀ Àwọn Ìjọ Àgbáyé yìí, ohun náà lo jẹ́. Yoo sọ gbogbo wa di ọkan. Oh, iyẹn nikan ni."

Àti pé àwọn mìíràn wí pé, "Kínni, ti eṣu ni! Èyí sì wà nínú Ìwé Mímọ́."

Lẹ́yìn náà ọkùnrin tí kò ni àkókò láti gbàdúrà, ki ó sì wá a, ó sọ pe, "Áà, gbàgbé rẹ̀." Gbagbe? O jẹ ... nipasẹ alaye rẹ, arakunrin, nipa ipo rẹ, nipa ọrọ ti o gba, yoo ran ọ lọ si ibi opin-ajo ayeraye rẹ nibiti iwọ yoo wa laelae. Maṣe ṣe iyẹn.

53 O yẹ ki a joko nigbati iru eyi ba dide, ninu ibeere kan.... Bi ti ọjọ Jesu; nígbà tí wọ́n dé, ìjọ náà sọ pé, "Ah, janduku lásán ni. Ko si nkankan nipa Rẹ."

Ṣùgbọ́n ọ̀kan wí pé, "Ẹ wa Ìwé Mímọ́." Ó sọ pé, "Nínú wọn, ni ẹ rò pé ẹ ní ìyè àìnípẹ̀kun, wọ́n sì sọ ẹni tí èmi jẹ́ fún yín."

Lẹyin naa awọn ọkunrin, awọn obinrin, ti eyikeyi ipo Kristẹni, tabi ti o ni ifẹ si ibi ayeraye wọn, o yẹ ki o wa Iwe-mimọ ki o rii ẹni ti Oun jẹ. Nigbanaa ibeere naa kii yoo jẹ, "Ta ni Eleyi?" Wọn sọ pe, "O wa nihin!" Iyatọ niyẹn. Wo, awọn eniyan ni, wọn kan ni ọna yẹn ni. Diẹ ninu wọn ni a yàn si. O ṣòro lati sọ bẹẹ, ṣugbọn o jẹ otitọ. O fihan, wo.

54 Bayi, loni, diẹ ninu wọn sọ pe, "Mo gba Ọrọ naa gbọ. Òtítọ́ ni Ọ̀rọ̀ náà; gbogbo Ọrọ naa."

Awọn miiran sọ pe, "Ah, awọn oluṣọ-aguntan wa lọ kọ iru ekọ bẹẹ…. Wọn mọ ohun ti wọn yoo sọ nipa iyẹn."

Omiiran sọ pe, "O dara, Emi ko mọ. Mo darapọ mọ eyi. Emi ko fẹran rẹ. Mo lọ si ibiti mo ti darapọ mọ eyi ni. Emi ko mọ ti eyi ti o yẹ lati jẹ," wo. Iyẹn ni bi o ti o jẹ nigbana, iru ogunlọgọ ero naa. O jẹ ọna yẹn nigbagbogbo, lati ibẹrẹ, ati pe nigbagbogbo lo jẹ bẹẹ.

55 Nisisinyi, jẹ ki a wo inu Bibeli lati mọ bí iyẹn ba tọna; fun iṣẹju diẹ bayi ... Adamu .... Ni ibẹrẹ o bẹrẹ bi eyi, ọna ti a gba ni loni, ko ti yipada rara. Ádámù jẹ́ onígbàgbọ́. Sátánì jẹ́ aláìgbàgbọ́; ko gba Ọrọ gbọ. Nítorí náà, ó mu Éfà, tí kò mọ̀ bóyá ó tọ́ tàbí ko tọ́, wò ó. Satani, alaigbagbọ naa...Ọlọrun sọ pe, "Ni ọjọ ti iwọ ba jẹ ninu rẹ, ọjọ yẹn ni iwọ yoo ku."

Sátánì sọ pé, "Kò ri bẹ́ẹ̀." Wò o, oun kò si gbagbọ́. Ádámù gbà á gbọ́. Nitorina o ṣiṣẹ lori eyi ti o wa laarin. Wọn ko le sọ… oun ko le sọ.

56 Ní báyìí, ṣàkíyèsí, obìnrin tó wà níhìn-ín dúró fún ìjọ ẹ̀sìn ọjọ́ iwájú tí wọ́n ń pè ní ìyàwó. Gbogbo rẹ bẹrẹ ninu Genesisi. Irugbin ni. Iwọ bẹrẹ ni Genesisi; iwọ yoo ri aworan rẹ taara, wo. Bayi, o jẹ apẹrẹ ijọ ti ode oni

nitori diẹ ninu wọn sọ pe a o mu ijọ awọn alagba, ati ti Lutherans, ati diẹ ninu wọn wa ni ayika, awọn oniṣowo wọnyi ati bẹẹbẹẹ lọ, “A fẹ lati ni…. Baptismu ti Ẹmi Mimọ. A fẹ lati gba.”

Ṣe o mọ ọjọ ti a wa ninu rẹ bi? Wo? O le jẹ pe wọn ko mọ. Ǹjẹ́ o mọ̀ pé Jésù sọ pé, “Nígbà tí àwọn, wúńdíá to ń sùn . . .

Nisisinyi, ranti, awọn wundia ti o sùn wa lati beere fun epo. O ti fi edidi di gbogbo wọn sita. Ko ri gba. Ko ri gba. Ṣe o mọ pe lẹyin ti iyawo lọ tan, goke lọ si ọrun, ijọ yoo si tun maa tẹsiwaju ti awọn eniyan yoo maa ro pe a gba awọn la ati ninu ohun gbogbo gẹgẹ bi nwọn ti n ṣe nigbagbogbo. Wọn ntẹ̀síwájú gẹ́gẹ́ bí ó ti rí ní àwọn ọjọ́ Nóà. Wọ́n ń jẹun, wọ́n sì ń mu ati gbogbo nǹkan bí wọ́n ṣe máa ń ṣe. Wọn ko mọ, ṣugbọn ilẹkun ti ti. Ati pe o le jẹ pe, ẹyin ọrẹ, ilẹkun le tii nigbakugba. Boya o si ti ti bayi, ni bi mo ṣe mọ. A ko mọ.

57 Diẹ ninu wọn nikan ni yoo le tẹsiwaju lọ. A mọ̀ pé “Bí ó ti rí ní ọjọ́ Nóà, ọkàn mẹ́jọ ni a gba là, bẹ́ẹ̀ ni yóò sì rí nígbà dídé Ọmọ ènìyàn.” Ọkan diẹ ni a o gbala. Emi ko sọ pe mẹjọ. O le jẹ ẹgbẹrun tabi .... Emi ko mọ iye wọn. Ẹgbaa mẹjọ. Emi ko mọ. Milionu mẹjọ...

Ṣùgbọ́n wo o, ìyàwó náà kì yóò jẹ́ tí àwùjọ kékeré wà níhìn-ín nikan lórí ilẹ̀ ayé nísinsìnyí. Nígbà tí ìṣọ́ keje, nígbà tí O dé, gbogbo àwọn wundia náà jí, wọ́n si tún fitílà wọn ṣe. Lati ẹyin wa, gbogbo awọn ti o gba Ọrọ-ami-ororo gbọ́ ni gbogbo akoko. Jade wa, gẹgẹbi ile-onigun-mẹrin ti olori ṣonṣo, to fẹ̀ ni isalẹ, o si goke wa… Ṣugbọn okuta ibori gbọdọ wa lati gbe gbogbo nkan naa lati sọ di ile-onigun-mẹrin naa. Woo, mu papọ. Bayi, iyawo yoo jẹ ti gbogbo awọn ti o ti la akoko aye ja, ti o gbagbọ ti wọn si ti gba kristi gẹgẹbi Olugbala wọn.

58 Bayi, Eefa ko ni idaniloju. Adamu si wi fun u pe, “Njẹ nisisiyi, Ọlọrun wipe, Ololufẹ, ni ọjọ́ na ti iwọ ba jẹ ninu rẹ̀, li ọjọ na ni iwọ yoo kú.” Ṣùgbọ́n ó sọ pé... Sátánì sọ pé, “Dájúdájú ìyẹn kò lè jẹ́ òtítọ́. O ro pe Baba kan yoo ṣe si awọn ọmọ rẹ…. Iru nkan bi iyẹn. Nitootọ ko ri bẹẹ,” wo.

Ati kini o yi pada si nikẹyin? O yipada si “dajudaju.” Ati pe iyẹn gan-an ni ohun ti ijọ ṣe loni, ni deede. “Ah, nitootọ.... A jẹ ijọ nla kan. A jẹ ẹni nla. A ti pẹ .... Gbogbo nkan wọnyi ti wọn pe ni ẹṣin-were nihin, nkan wọnyi ti wọn npe ni baptisi ti Ẹmi Mimọ ati ohun gbogbo.. Isọkusọ niyẹn! Wo, iyẹn…. Ko si iru nkan bii iyẹn. Ah, nitootọ ... Mo san idamẹwa. Mo lọ si ijọ. Iya mi lọ si awọn.... Nitootọ Ọlọrun....” Ṣugbọn Ọlọrun sọ yatọ si! [alafo wa lori teepu.] Woo, ti Laodikea yii, lati fihan pe o ti pari; pe o ti fi edidi di tẹlẹ nibẹ, ati pe Kristi wa ni ita. Ko sọ pe O tun pada wa, o mọ. Nitorina a rii loni, o mu Ọrọ naa jade, gẹgẹ bi o ti jẹ nigba gbogbo.

59 Ni bayi, ṣe akiyesi, Mose, Ọrọ ẹni-ami-ororo… tabi boya a pe e…. Mo nireti pe iwọ yoo loye, nigbati mo ba sọ pe oun ni Messiah naa. Òun ni Ọ̀rọ̀ ẹni àmì òróró tí a ti ṣèlérí fún ọjọ́ yẹn. Iyẹn ni ohun Mose jẹ! Ṣe o gba iyẹn gbọ? Dájúdájú, ọ̀rọ̀ náà—ọ̀rọ̀ náà Mèsáyà túmọ̀ sí “ẹni àmì òróró naa.” Wo? Wàyí o, Nóà ni ẹni àmì òróró ti ọjọ́ rẹ̀. Abraham ti o sọ ... pe nibẹ yoo .... Awọn eniyan rẹ ti ṣe atipo fun irinwo ọdun ninu igbekun, a o si mu wọn jade nipa ọwọ agbara, ati ohun ti yoo fi han: iṣẹ-àmi rẹ ati iṣẹ-iyanu. awọn iran ti o si n bọ, ati ohun ti yoo ṣe. Mose si duro nibẹ̀, ọ̀rọ-ami-ororo ti ọjọ na. Ìdí nìyí tí ó fi lè fi ọwọ́ sí àyà. Kí nìdí? O duro niwaju Ọlọrun. Amin! Ògo ńlá Ṣekinah yí i ká. Gbogbo ìṣísẹ̀ tó gbe ló dúró fún Ọlọ́run. Iyẹn ni ibiti o yẹ ki ijọ duro si bayi. Bẹẹni! Dipo iyẹn, a ti wa ninu awọn ẹgbin ti awọn ijọ adamọ kan.

60 Ṣùgbọ́n a ti fa Mose mọra, ó sì yà sí ẹ̀gbẹ́ kan. Ọ̀wọ̀n iná náà sì dúró si nínú igbó náà. Níhìn-ín ni Mósè dúró sí tii ṣe ẹni ami-ororo. Kosi ẹniti o ṣiyemeji pe boya ko mọ ohun ti o n se. Awọn àmì ti a fi fun un nigbati o duro nibẹ pẹlu ọpá oluṣọ-agutan rẹ, ati pe o mọ pe iyẹn yoo jẹ ọpá naa ni aginjù. O di ejò, lẹyin naa o di etutu; ejo di etutu ninu aginju. Gbogbo ohun tí ó ṣe...àmì àti ohùn ti o ń bá àwọn ènìyàn náà sọ̀rọ̀ ni. Wo, ohun kan wa ti o ni asopọ pẹlu rẹ. Ó sì ṣeé ṣe kí Mósè fúnra rẹ̀ le má tiẹ̀ mọ̀ ọ́n, sugbọn òun ni Ọ̀rọ̀ ẹni-àmì-òróró ọjọ́ yẹn. Òun ni ìránṣẹ́ ẹni-àmì-òróró. Nítorí náà, bí òun bá jẹ́ òjíṣẹ́ wákàtí yẹn, òun ni Mèsáyà ti wákàtí yẹn. Òun ni ẹni-àmì-òróró naa.

